# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 879, LAGOS SATURDAY JULY 27 AUGUST 2 KOBO MEJI (2D) 1963

# Awon Oselu Ile Nigeria Fi Ase Si Wipe Ki Ayi Eto Ijoba Gbogbogbo Pada Nwon Ti Fi Oro Ofin Itimole Sapa Kan

EKO—Fun odidi ọjọ meji gbako ti awọn oselu aṣoju awọn ara ilu gbogbo igun mẹrẹrin ilẹ Nigeria fi ṣe ipade pataki kan ni ile igbimọ aṣofin ti o wa ni itosi Onikan (Race Course Road) ni ilu Eko, lati jiroro lori eto Ijọba Alailọba (Republic) ti nwọn ngbero lati gbe jade ninu oṣu October ti mbọ. Alhaji Ọlọla Abubaka Tafa Balewa ni o ṣe alaga ipade na, gbogbo ẹṣẹ awọn olotu ijọba ipinlẹ yoku lati Ariwa, Iwọ-Orun ati Ila Orun ni nwọn pe sibẹ pẹlu awọn olubadamọran wọn.

Nkan kinni ti nwon kọ jiroro lori rẹ ninu ipade na ni wipe ki gbogbo awọn aṣoju oṣelu fi ẹnu wọn sọkan ki nwọn si pa ohun pọ wipe asiko ti to lati yi eto ijọba gbogbogbo pada, ati wipe ti a ba ṣe atunṣe yi tan a o wa yi orukọ ilẹ Nigeria pada lati Federation of Nigeria si Republic of Nigeria.

A ko ni fi orukọ ọba binrin ilu Oyinbo bura mọ tabi ki a fi si iwaju ninu gbogbo eto iṣelu wa.

Bi eto yi ba joko tan gbogbo awọn aṣoju ilẹ wa ninu ile igbimọ nla ni yio dibo yan Baba ẹgbẹ fun Ijọba titun yi. Bonkẹlẹ si ni a o dibo na lati yan an ni ilẹ apapọ awọn aṣofin wa.

A gbọ wipe a ko ni mu awọn ọba ati ijoye nilu wa lọ si ile ẹjọ (Kotu) mọ.

## Ofin Itimole

Lori ofin itimọle tuntun ti nwọn ngbero lati da silẹ ni awọn ikọ ti o nwa si apejọ ipade na ṣe ariyanjiyan le lori pupọ, awọn oṣelu kan ni awọn fẹ ofin na, awọn kan si faake kọri wipe kiṣe ofin ti o ba oju mu rara, awọn mọ wipe awọn janduku kan wa nitotọ ti



Tafawa Balewa

nwọn ngbero lati doju ijọ-delẹ ṣugbọn awọn ti ni ofin na-lẹ ti awọn le lo fun iru awọn enia bẹ.

Awọn oṣelu ti nfẹ ki nwọn gbe ofin na jade ni ijọba ko la oju rẹ silẹ ki talubọ kowọ ọ, ki nwọn ba le fi ofin yi pa ero awọn enia bu ṣuku yi ni ijoba fi fẹ se eto ofin tuntun na, ṣugbọn ofin ti o yẹ ki nwọn ṣe ni eyi ti nwọn yio la ẹsẹ ti, enti nwọn ba fẹ lo timọle na ṣe fun un ti a ba ṣe alaye ẹsẹ re na fun tan, ki a si tun fun laye lati gbe ọrọ rẹ lọ si ile ejọ ti nwọn yio ti gbọ ẹjọ rẹ.

Nwọn si fi ijiroro eri ọrọ ofin na di igba miran.



Olu Akinfosile

### Awon Imale Faramo Eto Ilera Eko

# Awon Ara Ipinle Yoku Nfe Ti Won

EKO— eto ilera fun awọn ara ilu Eko ati awọn osiṣẹ Eko ti Dokita Majẹkodunmi fi igbakan gbe siwaju awọn igbimọ aṣofin ilẹ Nigeria, ti nwọn ni eto na din koko, ki o si gbe e siwaju awọn ara ilu ati awọn dokita on ṣegun ki nwọn yanju koko ti o wa nibẹ na ki nwọn to tun gbe wa siwaju awọn, ni a gbọ wipe gbogbo awọn Imale Eko ti fohun ṣọkan wipe awọn yio faramọ nitoripe a din wahala ati inira ti awọn nri nile iwosan (Hospital) ku.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

Eto Iwosan:

# Awon Dokita Eko Ni Oke Isoro Wa Ninu Eto Ilera Majekodunmi

Awọn dokita onisegun Oloyinbo ti nwọn da iṣẹ ṣe fun ara wọn (Nigerian Medical Association ti a npe wọn ni ede Oyinbo) ti gbe iwe atako t wọn jade lori eto ilera ti Dokita Moses Adeoye Majẹkodunmi, minisita alamojuto eto ilera gbogbo ilu Nigeria fẹ gbe jade fun awọn oṣiṣẹ ati awọn ara Eko; nwọn si to awọn oko ti awọn ri ni iṣoro ninu eto tuntun na.

## Eto Owo

Nwọn ni bi gbogbo awọn oṣiṣẹ Eko ti nwọn nsan owo fun loṣoṣu nibi ṣe wọn ba gb ki nwọn gbe eto ilera na jade a jẹ wipe olowo-fowo-raku ni awọn fọwọ si funra wọn.

Nwọn ni Dokita Halevi ti Dokita Majẹkodunmi mu wa lati wa ṣe iwadi isoro ti awọn dokita ni ti ko nje ki nwọn tete da awọn enia ti nhan nile iwosan ni awọn enia ko kọ lati ma sanwo fun itoju wọn, ṣugbọn ko mọ wipe ise apa awọn dokita ijọba lori, nwọn ni ẹgbaa-o-le adọta enia (2,050) ti dokita kọkan ni lati da lohun lojo kan ni ile iwosan.

## Ilu Oyinbo Nko?

Awọn dokita olowo ni eto ko ri bẹ nilu Oyinbo, nwọn ni dokita kọkan ko gbọdọ toju alaisan ti o ju igba o-le ọdunrun (2,300 enia) ; Ijọba ilu Oyinbo si tun fun dokita kọkan ninu awọn dokita onişegun Oyinbo ti nwọn nda iṣẹ ṣe fun ara won ni aye lati ni ẹgbẹjidinlogun-o-din ogọrun (3,500) enia ti yio ma toju gba owo lọwọ wọn.

Nwọn ni awọn dokita wa pupọ to l'Eko, eto alamojuto ni kan ni ko ja gaan to, paapa egbogi ko si ti awọn dokita ijọba nwọnyi le ri lo.

## Kini Fa Owo?

Nwọn ni ni iwọn idunta pọnun mẹta, şile kan ati kobọ meje ni Ijọba nna lori enia kọkan ti nwon ngbe ilu Eko; ni ilu awọn Hausa Ijọba wọn nna şile mẹta pere; şile mẹrin ati kọbọ meje ni Ijọba Ilu Orun nna lori awọn enia tirẹ; ni Ipinlẹ Ila Orun şile meje ati kọbọ meje ni işiro owo ti awọn Ijọba ib; ni awọn nna lori awọn enia ipinle na.

Kinni o tun wa fa a ti Ijọbafi sọ wipe ki awọn ara ilu Eko tun ma wa san owo oṣoṣu ki nwọn to le gba itoju nile iwosan ? Ijọba ilu Eko nikan ni o nna wo pupọ ju lori ile iwosan ni gbogbo ile Nigeria.

Wo iyoku loju ewe kejo

## Awon Soja Wa Nilu Oyinbo



Aworan yi ni ti awọn sojaomo ile Nigeria ati ilu Saro (Sierra-Leone) ti nwon lo kọ iṣẹ si ni ilu Oyinbo nigbati nwọn nṣe ida raya ibiti nwọn ti nkọṣẹ na ninu papa gbalansa kan lẹba London.


**BE TALLER**

Increase your Height. Details free. Add :— C.T. Hospital, Azad Market, Delhi 6, India.



## LAGOS RACE CLUB

SATURDAYS 27th JULY, 3rd, 10th & 17th AUGUST. 963.
Racing Starts at 3.00 p.m. each day of the Meeting

DECLARATION.
Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1 30 p.m. and 2 p.m. on Racing Days.

ADMISSION: 3/- PER DAY.
including Entertainment Tax.

CHILDREN
No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Membe s Enclosure.

SWEEPSTAKE.
On each day's race Meeting a Sweepstake will be drawn on the number of Admission Tickets. 1st will be paid £2 10/-, 2nd £1 10/- and 3rd 10/-.

## Majekodunmi Pegede

# Alaye Eto Ilera Ti Ijoba Titun Fe Gbe Jade Fara Eko

O to iwọn nkan bi oṣu mẹta gbako nisisiyi ti Dokita Moses Adekoyejọ Majẹkodunmi, tiṣe Minisita alamojuto eto ilera fun Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria gbe eto ilera aragbabu kan jade fun gbogbo awọn enia ti nwọn nṣe iṣe l'Eko, Ebute-Metta, Yaba ati Suru Lere wipe ki o le jẹ irọrun fun gbogbo wọn lati ma ni anfani fun itoju nigbati nwọn ba nṣe aisan.

### Kin o Faa ?

Ko si nkan ti o fa iru eto ilera bayi ju ikunsinu ti o ti wa lati ọpọlọpọ ọdun sẹhin larin awọn ara ilu Eko pẹlu awon oniṣegun dokita nwọnyi ti nwọn nṣe iṣẹ nile iwosan ijọba lọ.

Ogunlọgọ enia ọkunrin, lobinrin lọdọmode ati lagba ni nwon nji ni owurọ kutukutu lọ si ile-iwosan ti nwọn ko ni ri dokita da wọn lohun lasiko; ọpọlọpọ ko tilẹ nfoju kan dokita rara ti nwọn yio fi lọ sile wọn.

Awọn alakoso paapa ri wipe otitọ ni inira wa fun ara ile lori ile iwosan ti nwọn nlọ. ọpọlọpọ igba ni ọmọ ọwọ nku si ẹsẹ riyawọn nibiti nwọn ndu-o de dokita fun itọju.

### Tabi Alamojuto Ni ?

Awọn alakoso Ijọba wa ri wipe ko si nkan ti o dara ju wipe ki awọn wa ọna ti awọn yio fi ṣe atunṣe eto ilera ilu Eko lọ. Eleyi ni o mu ki Ijọba Apapọṣẹ ilu Nigeria gba dokita olokiki kan lati ilu okere ti orukọ rẹ nje H S Halevi wipe ki o wa ba awọn ṣe iwadi lori ọna ti awọn ba le gba ti itọju awọn alaisan ilu Eko yio fi di ghẹfẹ fun awọn ara ilu ati awọn dokita ti o ntọju wọn.

Olokiki kakiri agbaiye lori iṣẹ abojuto awọn ile-iwosan ni Dokita Halevi ti awọn Ijọba gbe iṣẹ iwadi na fun nṣe. O si ṣe iṣẹ iwadi na daradara. Lori agbeyọri iwadi rẹ ni Minisita alamojuto eto ilera fun Ijọba Apapọṣe: Dokita Majẹkodunmi, fi gbe iwe eto ilera aragbabu na jade laipẹ yi wipe ki ijoko awọn aṣofin fọwọ si i ki awọn le ma ba iṣẹ lọ lori eto na.

### Atako Wa

Gbara ti nwọn ti gbe iwe eto ilera na jade ni awọn dokita ti nwọn nda iṣẹ fun ara wọn ti bẹrẹsi tako; nwọn ni minista alamojuto eto ilera ko pe awọn ni enia ti ko fi fi imọ awọn si eto na.

Eleyi ni iwe alaye ti Ijọba tẹ jade lori eto ilera na. Bakanna ni a o si tun tẹ eyiti o jẹ koko ninu iwe awọn atako ti awọn dokita ti nwọn nda iṣẹ ṣe fun ra wọn ṣe. O ya ẹ bẹrẹsi ka alaye Ijọba; "Iwadi ti Doktia Halevi yi. . . .

( W o yoku loju ewe kẹfa )

---

Kilo Fa Apinsapo:

## Olopa Mba Baba Oniwayo Pulu Sejo

YABA—Ogbẹni kan ti o nṣe iṣẹ akọwe a mba ni ṣiro owo ti nwọn nipe orukọ rẹ njẹ Adetunji Olokodana ti o mba awọn ẹgbẹ onisowo ti nfi ere bọlu (ball) atẹṣẹgba ṣe tẹtẹ fun ara ilu ti orukọ ẹgbẹ onisowo ara Pan Alecan Pool Ltd. ni Mushin ni lọsọsẹ ni awọn oga iṣẹ na npin irinwo pọnun o le diẹ larin ara wọn ninu owo olowo ti nwọn ba pa.

Ọgbẹni Olokodana bẹrẹsi ṣe alaye yi niwaju Adajọ Kotu awọn Ọlọpa ni Yaba nigbati nwọn bẹrẹsi ro ẹjọ ẹsun ONIWAYO ti awọn ọlọpa fi ẹkan ninu awọn oga ile iṣẹ pulu (Pools) na ti nwọn npe ni Anthony Taiwo Ọkẹowosun

Awọn Ọlọpa ni okan ninu awọn enia ti nwọn nta tẹtẹ-pulu lọdọ wọn, Ganiyu Owoyẹle fi pulu tirẹ jẹ ẹgbẹrin-din-logoji pọnun (£7,233 13 6d) lọdọ wọn, dipo ki nwọn ko owo rẹ fun nṣe ni nwọn yi iwe ti Owoyẹle fi ta tẹtẹ na da si bamirao.

Ki Olokodana to pari ẹri tirẹ, o ni ọga-agba ibi iṣẹ na, Ọgbẹni Ọlatunde Vincent ni nwọn npin ni owo ti o ba pọju ninu owo a-pa sapa wọn ọsọọsẹ.

Nwọn ko ti pari ẹjọ riro na.

---

## E Ka Irohin Ayiluka

loju Ewe Karun

# ELETI—OFE

(A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 879 SATURDAY JULY 27-AUGUST 2ND 1963


Oro Olotu :

## Ofin Isemo Tuntun

Awọn Yoruba a ma pa owe wipe: agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ tuntun wọ—bẹni. Awa oniwe irohin ilẹ Nigeria gbọ ọrọ kan ti o ta si wa leti wipe awọn alakoso Ijọba npete pero lati gbe ofin ola kan jada nipa ISEMỌ awọn ti o ba fẹ doju Ijọba bolẹ tabi awọn ti ẹnu wọn ba gbọrọ kọrọ.

Awa oniwe irohin 'Eleti-Ọfẹ' gẹgẹbi agbọrandun ara ilu fi iwe Ọrọ-Olotu wa ti ọsẹ yi bẹ awọn alakoso (Premier) Ijọba wa mererin ki nwọn jọwọ ki nwọn maṣe bi nwọn ti to lori ọrọ OFIN ISEMỌ tuntun na ti nwọn fẹ gbe jade. Nitotọ awọn janduku enia wa ni igboro, ko si si ibiti ẹṣẹ ko si.

### Ki A Ma Ri i

O kari-aiye ni ọrọ awọn janduku oṣelu ti nwọn wa kakiri gbogbo inu aiye nisisiyi. Bi o ti wa laria awa ara lodude ni o tun wa laria awọn alawọfunfun. Ti a ba fi oju agba wo ofin tuntun ti nwọn fẹ gbe jade na a o ri wipe idẹra ti o ti wa fun wa, ti o njẹ ki awọn aladugbo wa ni ilu miran ma pe wa ni ilu IJỌBA ỌMỌLUWABI ni a fẹ ta danu fun anfani ara wa.

Koko ti o buru ti o wa ninu ofin na ti awọn alakoso wa le tun lo ofin ihamọ na fun ni wipe nwọn le lo fun awọn ti nwọn ba fẹ lọgun aṣiṣe iranṣẹ ijọba (minisita) ti awọn kan ba ri wipe iwa rẹ ko dara, yala o ko ikan mọkan ni, tabi o ngba owo ẹhin ni tabi o huwa buruku kan ti ko boju mu ni.

### Ida Olojumeji Ni

Bi awọn aṣofin wa ba ti fọwọ sofin na ki ẹ mọ wipe nwọn ti gbe ida Olojumeji le awọn enia kan lọwọ wipe ki nwọn ma bẹ wa lori bi o ti wu wọn nijẹn. Ẹnikẹni ti nwọn ba ti koo fun, ko si ọran ti nlọ si Kotu lati gbọ tẹnu ẹni nibẹ, ọran a ngba lọya ko si nibẹ, a fi A.IU ỌLỌRUN loku fun oluwarẹ.

Nitotọ a ni anu ju ara wa lọ; oṣelu alakoso Ijọba miran wa anu ni o fi nlo aṣẹ Ijọba tirẹ, ominira si wa suna alakoso (Premier) KOGBEREGBE, ni nwọn fun, o si jẹ oye BABA ALAGBARA bi o ba si ti fẹ ni o le lo ida olojumeji ofin na si.

Nitorina a bẹ ẹnyin oṣelu wa, ẹnyin aṣofin wa ki ẹ jọwọ, ki ẹ ro ọrọ ofin isemọle yi daradara ki ẹ to lọwọ si i, nitori ijamba ti o mbẹ nibẹ lẹhin ọla. Awa Eleti—Ọfẹ ti sọ ti wa na o iyoku dọwọ yin.

## Iwe Si Olotu

# Olorun Ko Bi Omo Rara ?

O ti pẹ ti a ti ma ngbọro kan lẹnu ọpọlọpọ awọn ara wa ti awọn fi ẹsin won lẹ e Anabi Isa ọmọ Mariamọ (Jesu), ti nwọn ma nsọ o, ti nwọn si ma nfi ṣe iwasu nibikibi wipe ỌLỌRUNMẸTALỌKAN ni o wa.

Iyẹn ni pe. ỌLỌRUN BABA, ỌLỌRUN ỌMỌ ati ỌLỌRUN ẸMI MIMỌ (ọna mẹta ni Ọlọrun ti o wa )

Ẹ jọwọ ẹ se gafara fun mi, Ọlọrun kan ṣoṣo ni o wa. Mo tun fi orukọ Anabi rẹ bẹ yin, Ọlọrun ko bi ọmọ kan rara, a ko si ri eniti o le sọ wipe on ri ka yala ninu iwe Bibeli tabi ninu Alukurani wipe iya kan ni o bi Ọlọrun alara paapa.

Ti ẹ ba ka iwe Korani ori 19; ẹsẹ 30-36 ẹ o ri wipe ẹri wa wipe Anabi Isa (Jesu kiṣe ọmọ Ọlọrun rara Anabi Isa paapa sọ bayi ninu Alukurani wipe "Ẹni Ọlọrun ni mo jẹ, Ọlọrun na si fun mi ni tira (taureta), a si ṣe mi ni ojiṣẹ Ọlọrun, Ọlọrun si ṣe mi ni eniti o ni alubarika ni ibikibi ti mo ba wa.

"A sọ asọtẹlẹ fun mi Ọlọrun fun mi ni ọjọ ti a bi ni saiye laikoni baba ati ọjọ ti emi yio ku ati ọjọ ti a o ji mi dide ninu boji.

Ṣe ẹnyin na wa ri nisisiyi lati sọ wipe Ọlọrun bi ọmọ? Abọ mi niyi o, Olotu, ajinde ara ki o ma jẹ fun yin.

Eko

Emi ni,
Alufa S A Bawa

---

### Ibosi Ole Ni Jankara !

Ẹ jọwọ ẹ fun mi laye diẹ ki nle kin Ọgbẹni Atoyebi lẹhin fun ọrọ awọn ọmọ jaguda ti o ni awọn ko je ki awọn ara ilu sinmi ti awọn ba ti gba opo po ọna Jankara l'Eko.

Mo kan saara si Ọgbẹni Atoyebi na fun aṣiri awọn ọmọ jaguda atatẹtẹ na. Ọrọ wọn ko ṣe ma sọ ni; ijagbagbogbo ni nwọn ma nda enia lọna, nwọn a ni afi bi oluwarẹ ba fowo bẹ awọn ki o to lọ.

Awọn ọlọpa wa ibi ara si ọrọ wọn, a fi ibiti nwọn yio ba ti ri owo riba gba.

Ẹ ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi, iṣẹ yin a ma lọ soke.

Atobajẹ, Agege

Emi ni,
S. Amọkẹ

---

### Eleyi Ti Je Olopa Eko ?

Olotu, ẹ jọwọ gba mi laye ninu iwe irohin yin lati kesi awọn ọlọpa Ijọba Ipinlẹ Eko ki nwọn jọwọ ba wa kesi awọn ọlọpa Ijọba Ibilẹ Eko (Lagos Town Council Police) ki nwọn ye damu awọn ọmọ wa agbalagba ti nwọn nkiri ọja.

Tabi ọmọ ọdun mẹdọgbọn ko dagba to lati ma kiri ọja? Awọn ọlọpa yi ko njẹ ki awọn agbalagba ọmọbinrin yi sinmi rara bi nwọn ba ti ri ọja lori wọn.

Ole nikan ni a gbọ wipe ọlọpa nmu kakiri; ewo ni ti nwọn nwa ọjẹ oojọ wọn kiri? Bi awọn ọmọ wa ko ba ran wa lọwọ ki a ṣe iṣẹ, ki a lowo lọwọ nibo ni ao ti ri owo-ori san fua Ijọba?

A ko ti'ẹ mọ bi awọn alamojuto eto Ijọba ni o nfu awọn ọlọpa na tabi awọn ara wọn ni.

Abọ mi niyi o, Olotu, iwaju ni ẹ o ma lọ o.

Erelu Street, Eko.

Emi ni,
Josaya Ọjẹ Ajiṣafẹ,

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

Lati Owo Ayiluka

## OFIN OMOLUWABI

Ẹnyin okawe mi wahala mi po d ẹ ninu ọsẹ ti o koja yi, ojojumọ ni mo nlọ si ipade bi baba ẹgbẹ awọn omọ ẹ LOKO ni ogba RELUWE ni Ebute Metta tabi awọn oṣiṣẹ Apapa ti aiye aijo. Mo tun lọ si ipade awọn dokita ilu Eko ti nwọn fi aa e kori wipe awọn ko fẹ ki enikan fọ ikoko ọbẹ awọn. Mo tun lọ si apejọ ti ọre mi, Dokita Koye Majẹkodunmi ṣe ier eto ilera kan ti o fẹ gbe jade fun awọn ara . ko.

Mo tun ta kan lọ si Abeokuta ilu Ẹgba lati lọ wo nkan ti awon afọbaje Ẹgba fẹ ṣe lori ọrọ Ọba Alake. Nigbati mo de Ake, mo here ọrẹ mi, Ọmọba SAG, boya ẹ ko mọ ẹniti o ijẹ bẹ, Adeshina Ọmọ Ọba

( Wo yoku loju ewe kejọ )


## Jẹki owo rẹ ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamọ Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rẹ fi owo ti o pa si Ile Ipamọ owo. Fi sabẹ abo nitori igbati o ba nfẹ owo lati fi ra ohun ti iwọ o gbin sinu oko, ogun ilẹdu tabi irinṣẹ. Nigbati owo rẹ ba si wà ninu ile ipamọ owo ere a ma ti inu rẹ jade ni igba de' gbà.



### 'Ẹ FI OWO YIN PAMỌ SIBẸ'

Barclays Bank ti se opolopo aworan oni sinima ti ẹ̀ni mọ dada to si nderin pani, boya ẹ ti ri wọn tẹlẹ. Eyi jamọ itan nipa awọn agbẹ mẹta ti wọn ko eso oko wọn lọ si ọja. Endokan wọn pa owo pupọ.



Ọkan ninu agbẹ nwọnyi si nkọrin lọ sile to nk'igbe ki gbogbo enia le mọ wipe o ti di olowo. Awọn ọrẹ rẹ si nyà owo lọwọ rẹ, iyawo rẹ ko si ohunkohun gbà rara. Agbẹ keji fi owo tirẹ pamọ si abẹ ibusun, nigbọn ole kan ji diẹ lọ ninu rẹ ni alẹ, kokoro tun jẹ iyoku.

Agbẹ kẹta ṣogbọn ju wọn lọ.

Gbogbo owo rẹ lo ko lọ tàrata sile Ipamọ Owo rẹ Barclays, ki o ba le ra ohun toba fẹ lati gbin sinu oko ni akoko ati irinṣẹ pẹlu.

Ranti wipe, owo rẹ wà labẹ abo ninu Barclays Bank.

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile iṣẹ wọn mbẹ kakiri ni orilẹ ede yi.*

# Alaye Eto Ijoba

## (O bere loju ewe keta)

"Iwadi Dokita Halevi yi şe fihan pe awọn enia igboro ilu ko kü şe ope tabi oponu, nwọn si ni ınọ ati ọgbọn to lati lo gbogbo anfani ti awari lori ọrọ egbogi ode oni le şe fun iwosan ati imunilarada ọmọ ẹda. Iwadi na tun fihan pe gbogbo awọn enia ilu na ni awọn nşe gudugudu meje, ti nwọn si nna ọpọlọpọ owo lori itọju laisan ara wọn tabi ti ọmọ iyawo tabi molẹbi miran ti o sun mọ wọn dada. Nigba miran paapa owo geregere ni awọn enia ilu Eko nsan labẹ işoro lati ba le fi tọju ara wọn lọdọ awọn dokita ti nwọn nda işẹ şe fun ara wọn ati fun rira egbogi lọdọ awọn ti npo ogun.

Gẹgẹbi işoro ti o şe, Dọkita Halevi nfi ye ni pe awọn enia ilu Eko na nkan bi adọta ọkẹ pọnun lọdọdun, eyiyi ni ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun pọun (£1,000,000) fun itoju aisan ni ọdọ 'awọn dọkita' ti nwọn nda işẹ şe fun ara wọn. Eyi ko si lara inawo miran ti o to nkan bi ọkẹ marundinladọta pọnun, ẹgbẹrun lọna edẹgbẹrun pọun (£900,000,) ti nwọn fi nra egbogi lọdọ awọn ti npo egbogi oyinbo fun tita,

### Lori Owo

Bi a ba şiro iye awọn enia ti nwọn wa ni ilu Eko si ọkẹ mẹdọgbọn enia, eyi yi ni ẹgbẹrun lọna ẹdẹgbẹta enia (5000,000,) inawo lori itọju aisan ati fun ilera yi yio ku sori pe ẹnikọkan na to pọnun mẹrin lọdọdun. Fun alaye, bi o ba jẹ wipe enia bi mẹrin tabi o din diẹ ni nwọn wa ni agbo ile kọkan, o wa jẹ wipe bale ile kọkan ni ilu Eko nna bi PONUN MẸDOGUN LỌDỌDUN fun itọju aisan awọn ẹbi rẹ.

Dokita Halevi wa da imọran ni opin iwadi ti o şe lori ọrọ yi wipe owo tabua ti awọn Eko nlo yi le şe ekojọpọ lati lo fun eto ilera ati itọju awọn alaisan ni ọna ti yio fun awọn enia ilu Eko ni itẹlọrun lori inawo wọn ju ti atẹhinwa lọ.

Nitorina, a fẹ ki o da olukuluku loju pe aba lati şe atunşe ati-afikun gbogbo eto işẹ ilera ati itọju awọn alaisan ni Eko yi waiye nitori iberr awọn dokita Ijọba ti nwọn nşe işẹ na ati nitori iya ti awọn enia ilu Eko papa ti jẹ fun ọpọlọpọ ọdun nitoripe awọn anfani fun ileri ati itọju awọn alaisan ti Ijọba pese si Eko ko to fun wọn.

### Sisan

Aba fun atunşe ati afikun eto işẹ ilera titun yi şe rẹgirẹgi pẹlu eto abojuto ati işakoso işẹ ilera ati itoju awọn alaisan gẹgẹbi awọn orilẹ-ede ọlaju iyoku kakiri agbaiye ti nşe eto yi ni ilẹ wọn.

(Koiti Pari)



(Oloye Majẹkodunmi)

## Akiyesi

**Eyi ni lati fi ikede fun gbogbo Enyin Onkawe wa wipe a fe Ki Ema ka irohin aladun.**

**E PO LOWO OJA YIN SINU Iwe Irohin Eleti-Ofe**

# Omi Le Awon Ara Ilu Kan Jade Ni Ghana

ẸKUASI (LẸBA SẸKỌNDI)—Ojo arọ mada ti o rọ ninu ọsẹ ti o kọja yi ti da nkan silẹ nilu Ghana; ni ilu kan ti nwọn npe ni Ẹkusi lẹba Sẹkondi ni a gbọ wipe o to irinwo awọn ara ilu na ti omi le kuro nilu ti o si gbe gbogbo ẹru wọn lọ.

Awọn onirohin ilu Ghana ni ọjọ meji gboko ni ojo-a-rọ-ma-da na fi rọ lọsan loru, ti omi si ya kakiri aria ilu ti o nwọ iyara awọn miran, gbogbo ibiti awọn ọmọde nsun si ni omi yusi.

A gbọ wipe Ọlọrun ko jẹki ẹmi şofo ninu ayasi omi na, şugbọn gbogbo awọn ti omi ba ile wọn jẹ ni awọn onişẹ ijọba fun alafia awọn ara ilu ti bawa agọ kan lati fi şe ibugbe titi nwọn yio fi mọ nkan ti nwọn yio şe fun wọn.

Gbogbo oke ti o wa ni ẹgbẹ ilu na ni omi ti ya silẹ,

### O Kari Aiye

O kari aiye ni ọrọ ojo ti o rọ titi lọsẹ ti o kọja na, a gbọ wipe agbabuyabu omi ni ti Abẹokuta, bẹna si ni ti Ibadan; gbogbo oju ọna mọto ni ojo na ti da koto si kakiri şugbọn a ko ti gbọ wipe Odo Kudẹti şe ẹnikan ni nkankan.

# Awon Obinrin Aba So Panpa Lori Awon Olopa

ABA—O lu edegbẹta awọn obinrin Ibo ti nwọn nta nkan lọja Aba ti nwọn ka ọwọ leri gba ile işẹ awọn ọlọpa lọ ti nwọn ni awọn fẹ-foju kan ọga awọn ọlọpa na ti orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni O Mba wipe awọn fẹ ki o ba awọn wa idi iku ti o pa onisowo kan, Ukonu Egbute, ara Ozu-Iten ti o ku ni ibẹrẹ oşu yi.

Gbara ti awọn okunrin ilu Ozu-Iteu na ti o wa lọja na ti ri awọn gbogbo obinrin yi nwọn nto lọwọ lọwọ lọ si ibişẹ awọn ọlọpa yi, ni awọn na ti ju nkan ti nwọn nşe silẹ ti awọn na gba ti wọn. Gbogbo wọn le ni ẹgbẹrun ẹnia.

Ẹsun ti nwọn fi awọn ọlọpa ọmọ işẹ Mba sun ni wipe awọn ni nwọn lu onişowo ara ilu awọn npa lọjọ ti tan pẹlu awọn ara ile rẹ jọ nja.

# Nigerians On The London Stage

LONDON—Two drama students from Nigeria had parts in a play, "The Green Pastures", presented in London last week at the Scala Theatre.

They were Miss Ebun Odutola, a third year student and Femi Euba, a first year student, both from Lagos. They are training at the Rose Bruford School of Speech and Drama at Sidcup, Kent, which put the show on for six performances.

Miss Odutola has now completed her course and is hoping to go to Paris to study mime before returning home to Nigeria.

During her training she has appeared in several television programmes and undertook special mime parts in a series of television films for overseas schools.

The students' performance received considerable praise in the British press.

## Conference

Nigeria is expected to be represented at the International Drama Conference to be featured at the Edinburgh International Festival which begins on August 18.

The six-day conference is the successor to last year's Festival when the International Writer's Conference was held. Among the topics for discussion are "to what extent is there room for nationalism in the theatre" and "should there be censorship."

## Nigerian Students Hold Congress In Britain

LONDON—Dr. Kenneth Dike, Vice-Chancellor and Principal of Ibadan University, has opened the ninth annual summer congress of the Nigerian Union of Great Britain and Ireland, being held in Leeds, Yorkshire, from July 21-27.

The Union, founded in 1948, has 8,000 members. Over 150 delegates from 40 branches of the Union will be attending the congress. Its theme is education and the future of Nigeria.

The problem of overseas students at British universities is the subject of a special lecture being delivered to the congress by Dr. D G Burns, Director of Commonwealth Studies at Leeds University's Institute of Education.

## British Voluntary Society Helps Nigerian Hospitals

LONDON — War On Want, a British voluntary society which gives help to the needy all over the world, last year gave £450,000 to many overseas countries including Nigeria.

The society in its anual report just published in London records grant maed towards buying equipment for Uburu Hospital and Iyi-Enu Hospital, both in Eastern Nigeria.

Other grants made by the society went towards building schools, hospitals, clinics, trade schools dormitories, ploughs, tractors and famine relief in many parts of the world including a number of coutries in Africa.

Comfortable and safe



A roomy 5-6 seater, space for lots of luggage, luxurious appointment, excellent finish, a very high standard of safety: these and many other welcome features you find in both of the 190 models and besides the 190 Diesel offers quite exceptional economy. Let us demonstrate by a trial run, free of any obligation, what excellent value these cars represent.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.): IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT HARCOURT: ABA.

SUB-DISTRIBUTORS:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

## Awon Imale Faramo Eto Ilera Eko

# Awon Ara Ipinle Yoku Nfe Ti Won

( O bere loju ewe kinni )

Oninhin wa ni Dokita Majekodunmi, minisita alamojuto eto ilera Ijoba ile Nigeria paapa ba gbogbo awon dokita ilu Eko sero nipa ale ijerin lori eto ile a wa. O ni awon alakoso Ijoba ti tun oro na ro, awon si ti pinnu lati mu isor ti owo sisan ti o wa nibe kuro.

Dokita Majekoduumi ni fun odun meta gbako ni Ijoba yio fi gbe eto ilera wa wo, nwon ko si ni gba owo lowo enikankan.

Akowe Onironin Eleti—Ofe ni inu gbogbo awon obinrin ara Eko ti o lo soja Oyingbo ni ana ni o dun mo nig ati awon akowe ibise eto ilera (Ministry of Health) ti nwon npin iwe alaye eto ilera na kiri beresi se alaye ni kikun fun won nse ikede wipe ofe pelu gbefe ni awon dokita yio ma da awon enia lohun ni ile iwosan ti awon asofin bi ti fowo si i nile igbimo.

Obinrin kan ti oruko re nje Towobola Ashake, ti mo ba pade ninu iso awon eleja ni boya eto yi a to le ka awon dokita ti nwon ngba owo-ehin lowo ku. "Bi o ba de ile iwosan (hospital) ti o ko ba ni OWO-RIBA lowo Oluware nlo sorun niyen.

Iya-afin Towobola ni opolopo awon dokita wa ni KO NI ANU RARA, OWO NIKAN ni nwon mo. Awon ara ilu oke ni awon na fe ki Ijoba ipinle awon na se iru eto ilera bayi fun awon.

# Eto Iwosan

(O bere loju ewe Keji)

### Alejo Gbe!

Awon dokita yi ni eto ilera Majekodunmi yi ko fe ri alejo lati ilu okere rara, bi awon obi re ba wa wo o lati ilu okere, ti nwon se amodi penren l'Eko nwon koran, a fi ti awon ba mu iwe owo-osu ti nwon nsan fun itoju ile iwosan lowo ki dokita to le ye won wo.

AKIYESI: A gbo irohin kan loru ana wipe Dokita Majekodunmi so wipe awon alakoso Ijoba ti se ikede wipe awon yio se eto ilera na lai gba owo lowo ara Eko fun odun meta gbako ti awon yio fi danan wo lati wo bi eto na yio ti lo si. Nwon si ti nko gbogbo ile iwosan ti awon yio lo si adugbo kokan l'Eko. —OLOTU

# Ayiluka Ni:

( O bere loju ewe karun )

### Ofin Maduro Wole De!

Mo ri nigbati mo de AKE, mo bere ore mi Omoro SAG, mo ni boya enyin okawe mi ko mo eniti o nj; oruko ti mo pe yi, Adesina Omo Oba Gbadebo ti mo nibo finrinfinrin wipe awon odo ni igun merin Abeokuta fe lori ite Oba Alake ni o nje be, sugbon ko si nite mo gbo pe o wa ni Ibadan lenu ise re. Ki nji oro na so fun yin, ko ti soba kan ni Ipebi Alake o. Omo Egba ni emi Ayiluka, lojo ti Oba ba wo Ipebi ma ji i so fun yin, emi na yio si to gege 'o si Abeokuta lati lo ye Oba Alake tuntun na si bi mo ti se ye ologbe Oba Ademola Keji si ni Ipebi ninu odun 1920.

### Awon Loya Faake Kori

Mo gbe wipe gbogbo awon omo egbe agbejoro (lawyer) ti o mbe ni ilu Nigeria ti faake kori wipe awon ko faramo ofin Ihamo ti awon alakoso Ijoba wa le gbe jade, emi Ayiluka paapa ko faramo nitoripe kise ofin Omoluwabi rara, ofin awon ehanna erankо igbe ni. Ko si ilukilu ti nwon ba gbe iru ofin ihamo na jade ti wahala ko nsi nibe.

Iru ofin bayi ko mu aya ilu bale nse ni o ma nmu okan awon ara ilu le siwaju si. Mo gbo wipe ida olojumeji ni ofin na ni, enikeni ni nwon le lo fun at pe nitori re ni nwon se ko ogba ewon Kirikiri ni Apapa.

### EBU IKA

Oro ofin na wa di oro Alufa atetashi kan ti o ni on riran wipe iyan nla yio mu ni ilu awon, oro iyan na ko si gbogun. Awon agbalagba ti o wa lodo re ni awon omo re ati iyawo re nko? O ni oju gbogbo awon ni yio to o.

Nitorina e je ki a fuju sile ki a ma woran; ati Hausa ati Ibo ati Yoruba, gbogbo wa ni oju wa yio ja a Eniti o ba gbin EBU-IKA omo re a jo nibe, esan ko gbogun. Iyen egun ti ofin ihamo pelu wahala ti o gbe pon sehin.

Ki egun yi ma ba po lori awa agbalagba ojo oni ti awon omo wa yio fi ma so wipe a ta oju wa sile ti nwon fi ase eleyi loju wa ni awon agbajo egbe awon loya (lawyer) ile Nigeria, awon oniwe irohin ati awon agbalagba ti nwon mo eni ti ati ise buruku ti ofin ihamo na le bi sile se nke kikan-kikan wipe ki awon oselu wa mase lowo nibe rara.

Mo gbo wipe oro igbe kike na ko nse ti emi Ayiluka nikan ati awon egbe loya pelu, awon omo akeko ile eko giga (University College) ni Ibadan paapa pelu awon oselu kan ninu awon omo egbe Alakuko (NCNC) awon ara ilu Enugu ni oro patipati ni, ki awon ma gbo o mo.

Nwon ni ika ti o ba se Ijoba awon ko wipe ki a ma gee. Ofi lati fiya je awon ti o ba tapa s'ijoba e ti wa nile, wa ni opo nwonyi?

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos, Box 467 Phone 23370; Editor: (Olotu) Ola. Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos